# Fi awọn lẹta àti nọmba ṣeré

Oníríuurú eré ni ó wà tí o lè fi àwọn lẹta àti nọmba ṣe, láti ara ìrí àti ohùn wọn tití dé kíkọ àwọn ọ̀rọ̀ tuntun tí wọ́n jọ ní lẹta ìbẹ̀rẹ̀ kan náà. O lè wá nọmba tí ọmọ rẹ lè dámọ̀, bíi nọmba ara ilẹ̀kùn rẹ tàbí ọjọ́ orí wọn, kí o sì ríi bóyá o lè rí àwọn nọmba yìí lórí àwọn ọkọ̀ nlá, ilé ìtajà tàbí àmì ojú ọ̀nà. Rántí pé àwọn lẹta àti nọmba n bẹ kaakiri!



**Olobó oníràwọ̀**
Ka òǹkà sókè pẹ̀lú ọmọ rẹ – wo iye àwọn ìgbésẹ̀ tí o nílò láti dé ibi ilẹ̀kùn iwajú ilé rẹ tàbí iye òpó iná tí tí o là kọjá bí o ti nlọ sí ibi ìgbafẹ́!

**Lọ́rọ̀ kúkurú**
Sọ̀rọ̀ nípa àwọn lẹta tí o lè rí nínú àfiránṣẹ́ àti ìwé-iroyin àtìgbàdégbà àtijọ́. Gé àwọn kan lára lẹta àwọn lẹta náà kí o sì ṣe àwòrán aláṣàpọ̀. Wò bóyá o lè rí lẹta àkọ́kọ́ orúkọ ọmọ rẹ. Tí kò bá tíì dá lẹta náà mọ̀ síbẹ̀, ya àwòrán rẹ̀ papọ̀ kí o sì ríi bóyá o lè ríi nígbà tí o bá jáde tí o sì nrìn káàkiri.

### *‘Mo nlọ ọgbà ìgbafẹ́’*

Ẹ jọ ṣe eré kan nípa ṣíṣe é ní àṣegbà kí o sọ ohun tí ìwọ yóò mú nígbà tí o bá nlọ sí ìrìnàjò sí ọgbà ìgbafẹ́. Ìlànà náà ni pé o lè mú àwọn nnkan tí ó ní ohùn ‘p’ nìkan (fún àpẹẹrẹ, ‘Mo nlọ sí ọgbà ìgbafẹ́, mo sì maa mú ounjẹ/ayékòótọ́/lẹẹdi ìkọ̀wé kan’). O lè jẹ ìgbádùn sís nípa ṣíṣe àyípadà ibi tí o nlọ (fún àpẹẹrẹ, sí etí òkun, níbi tí o ti lè mú àwọn ohun tí ó bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú ‘s’). Njẹ́ o lè rántí ohun gbogbo tí ìwọ yóò mú lọwọ?

**Lọ́rọ̀ kúkurú**
Láti ṣe kóríyá fún ọmọ rẹ láti lè tètè mọ ìwé kíkà, lo àwọn ohùn lẹta dípò àwọn orúkọ lẹta alfabẹ́ẹ̀ti. Lílo àwọn ohùn lẹta nígbà tí ẹ bá jọ nṣe àwọn eré bíi ‘mo nlọ síbi ìgbafẹ́’ tàbí ‘mo ṣe amí’, yóò ṣe ìrànlọ́wọ́ fún u láti pe àwọn ọ̀rọ̀ jáde bí ó ti nkọ́ bí a ti nkàwé.

### Plastisiini tàbí àwọn ìṣù lẹta fún ìṣeré

Ẹ gbiyanju kí ẹ jọ fi plastisiini ṣe àwọn àrà lẹta papọ̀, tàbí kí ẹ ṣe ìṣù lẹ́tà fún ìṣeré tiyin.

Ẹ ṣe àwọn àpòpọ̀ yii:

- ife ìyẹ̀fun-burẹdi lásán méjì
- ìdajì ife omi tútù
- ṣíbí òróró ìjẹun mẹ́ta
- ṣíbí omi ọsàn wẹ́wẹ́ kan (kì í ṣe dandan)
- ohun tó n fún ounjẹ láwọ̀ tàbí mú ounjẹ dán tó wù ọ́.

